Ẹnikẹni tí ó bá fi ohun miran búra yatọ si Ọlọhun Allah, onitọhun ti ṣe aigbagbọ tabi ka ní ó ti ṣẹbọ

Lati ọdọ ọmọ umar - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji - ó ní oun gbọ lẹnu ọkunrin kan ti n sọ pe: Rara o, oun fi Kaabah búra, ọmọ umar wa sọ fun un pe: A kò gbọdọ fi nnkan tó yatọ si Ọlọhun Allah búra, tori dajudaju emi gbọ Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - tí ń sọ pe: "Ẹnikẹni tí ó bá fi ohun miran búra yatọ si Ọlọhun Allah, onitọhun ti ṣe aigbagbọ tabi ka ní ó ti ṣẹbọ."

[O ni alaafia] [Abu Daud ati Tirmiziy ati Ahmad ni wọn gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n fún wa niroo pé ẹnikẹni tí ó bá fi nkan miran búra yatọ si Ọlọhun Allah ati awọn orukọ Rẹ ati awọn iroyin Rẹ, onitọhun ti ṣaigbagbọ si Ọlọhun, tabi ka ní ó ti ṣẹbọ pẹlu Rẹ; nítorí pé ìbúra ní í ṣe pẹ̀lú ìgbétítóbi fún nkan tí a fi búra, títóbi sì jẹ́ ti Ọlọ́hun Allah nìkan ṣoṣo; nitori naa, a kò gbọdọ bura pẹlu nkankan ayafi Ọlọhun Allah ati awọn orukọ Rẹ ati awọn iroyin Rẹ, Mimọ ni fun Un, Ati pé ìbúra yii wà ninu ẹbọ kekere; ṣùgbọ́n bí ẹni tí ó búra bá fi gbé títóbi fun nkan tó fi bura gẹgẹ bii ìgbétítóbi fún Ọlọ́hun Allah tàbí jù bẹ́ẹ́ lọ; nigba naa, ó ti wà ninu ẹbọ nla niyẹn.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3359